**Ogun Ita'ja**

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

**ELETI OFE**

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fiwe y[illegible] ṣ e ikede si awọn aṣoju iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe, ẹnikẹni ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranṣẹ si wa, ao pe lejọ, ako si ni fi iwe irohin ranṣẹ si enibẹ mọ.

VOL. XI No. 625. LAGOS, SATURDAY, MAY 23,—MAY 29, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Oku Ti Ati Sin, Lehin Osu Meta Yo Ese S'ode

ṢOGUNLẸ Ojo ti o rọ ni oru Alamisi mọju ọjọ Jimọ, oṣu May 21st-22nd 1959 rọ to bẹ gẹ ti o fi yọ ẹsẹ oku kan jade nilu Ṣogunlẹ. A gbọ wipe a ti sin oku yi to nkan bi oṣu mẹta si ẹba oko kan ni Ṣogunlẹ lẹgbẹ igi araba kan, nigbati ojo yi rọ titi ti ko da ni o ba hu gbomgbo igi yi lulẹ, eyi ni o ko ba oku ọdọmọkunrin kan ti a ti sin si itosi igi yi.

Nikia bi iṣẹju-Aaya ni awọn agbagba ilu na ti yara tun oku na sin. Wọn tun erupẹ bu si ni ori ati ẹsẹ.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

**ILEYA SHILLING FUND - JUNE, 1959.**

Depositors in the Ileya Shilling Fund are hereby reminded that, in accordance with the Regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday, 25th May, 1959.

Withdrawals can only be made by depositor in person and on production of his Passbook. In the case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, such application to be accompanied by the depositor's Passbook for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on the 25th June, 1959, and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Ileya.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the depositors' surnames on the date shown hereunder and contributors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to until Monday, 1st June, 1959.

| | | |
|---|---|---|
| A to B | Monday | 25th |
| C to H | Tuesday | 26th |
| I to N | Wednesday | 27th |
| O to R | Thursday | 28th |
| S to Z | Friday | 29th |
| A & O | Saturday | 30th |

For the year 1960, deposits will be taken as from Tuesday, 26th June, 1959.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER

## Akapo Owo Ijoba Ilu Oyinbo



Ẹniti a nwo aworan re yi ni Ọlọla-nla Derick Heathcoat Amory, M.P. ti awọn yan si ipo Akapo owo Ijọba ilu Oyinbo laipẹ yi. O ti je ọkan ninu awọn ẹgbẹ ti o mu opo Ijọba ilu Oyinbo dani lati ọdun 1951.

## A Toro Gafara

Loju ewe keji iwe wa yi ni a fi aworan Ọgbẹni Adisa Williams si ti a pe ni "Igi lẹhin Ọgba ẹgbẹ Ọlọpẹ" ati pe "O fi ilu Ibadan ṣe ibugbe nisisiyi"-eyi ko jẹ bẹ, Ọgbẹni A. Williams mbẹ nilu Oyinbo nisisiyi. Aṣikọ ni eyi, ẹ ṣe gafara.

## Enia Meje Sonu Nilu Enugu

ENUGU Larin osu tokoja irohin ti agbọ ni wipe en a meje sọnu larin ilu Enugu, eyi ara!

Eniti o ṣẹṣẹ sọnu ni ọmọ ọdun mẹrindilogun Cletus Okpa, ti o sọnu l'adugbo Silversmith ni Ogbeti Enugu lọjọ kejila oṣu yi.

## WON PA ỌMỌ WESINGISI KAN NILU OYINBO

LONDON. A gbọ irohin wipe awọn ọmọ ilu Gẹsi kan ko ara wọn lọ dena de ọmọkunrin kan ara ilẹ Wẹsingisi (West Indies) kan t' o npada bọ lati ile iwosan nitori ti o ti fi ika rẹ ṣe nwọn kọlu nigbati ode korọ kan, ibẹ ni nwọn si ti gun lọbẹ ni igba aiya nwọn si salọ.

Awọn ẹlẹgbẹ rẹ lori i ti nwọn si tun gbe lọ sile alaisan ki o to wa ku si ọhun, orukọ Wẹsingisi na njẹ Kalso Cochran, o si je ọkan ninu ọmọ enia dudu ilẹ Wẹsingisi ti o ngbe adugbo Notting Hill nilu London. A si gbọ wipe awọn ara ilu yi ti o ngbe London fẹrẹ le ni ẹgbaa mẹta.

## NWON DA OMOPUPA SILE

MUSHIN. Eti to ba gbọ alọ lo ngbọ abọ. Nipa irohin Ọgbẹni kan ti o jẹ gbajumọ ni agbegbe Mushin ti o njẹ Lawani Oluwo tabi eni'i ogunlọgọ awọn enia mọ ti nwọn si npe ni Ọmọ-pupa, ẹniti irohin rẹ jade ninu iwe wa yi lọsẹ to kọja wipe, o lugbadi awọn ọlọpa.

On ni Ọlọpa fi sun ẹsun pe o di ọlọpa lọwọ lẹnu iṣẹ rẹ, o si jẹki nwọn ta ẹmu ninu ile rẹ tayọ wakati ti nwọn ni lati ta mọ.

Eti to ba gbọ alọ, o yẹ ki o si gbọ abọ. Nigbati ejọ na dewaju adajọ Ọgbẹni L.E. Adesanya, o sọ wipe ọkunrin na, (Ọmọ-pupa) ko jebi eyikeyi ninu ẹsun ti awọn ọlọpa wa si lọrun na, ni adajọ ba da silẹ ki o ma lọ ni alafia.

Ọmọ-pupa o ku orire.

## Imototo Ni Iyi-Ara Enia

Dokita O. Adeniyi Jones Onişegun fun ilera ilu sọpe bi ilu kan ba dara, k'a mọ wipe eyini jẹ nipa imọtoto awọn ara ilu na. Bi ilu kan ba ti mọ to, bẹni awọn enia inu rẹ yio mọ to.

Bi ilu kan ba mọ eyi jẹ ọwọ ti awọn onilu fi mu ilu wọn. Dokita Jones sọrọ yi fun awọn ara abule Ijeshа o ni on fẹ ki gbogbo awọn enia fi ọwọ so ọwọ pọ pẹlu ijọba, ki a jijọ fi orikori pọ, ki a le se atunṣe gbogbo nkan ti ko nmu alafia wa silu.

## NWON BI OMO META SILE ALABIYAMO

EKO. Obinrin Adelebo kan iyawo Ọgbẹni Samuel ti o ngbe 14, Opopo Ojuelẹgba, ni Suru-Lere, ti a npe oruko rẹ ni Iyafin Adukẹ Samuel ni ẹniti o bi ọmọ mẹta sile Alabiyamọ ni Ita Ẹlẹiyẹ lọjọ Jimọ ọsẹ tokọja. Ọmọ obinrin meji ati ọkunrin kan.

Ibẹta ọmọ ti Adukẹ yi ni igba kẹrin ti nwọn ti bi ọmọ mẹta-mẹta sile Alabiyamo Ita Ẹlẹiyẹ lati ibẹrẹ ọdun yi.

Irohin ti a tun ri gbọ niti iyawo ọkunrin agbẹ kan ti a npe ni Malama Mairo tilu Daunaka ni agbegbe Katsina j'o tun bi ọmọ mẹta lẹkanṣoṣo.

A gbọ pe Gomina Ariwa ti ran Ajẹlẹ agba ki o lọ ki awọn obi awọn ọmọ ibẹta na l'orukọ Alaiyeluwa Ọba obinrin ilu Oyinbo Gẹsi.

## Oyinbo To Emu Wo Ni Ghana

ACCRA. Ọgbẹni Hugh Gaitskell ti oje ọkan ninu awọn asiwaju oselu nigboro ilu London lo lọ se abẹwo ile Ghana laipe yi.

Nigbati nwon nse eye fun Ogbeni Gaitskell nilu Accra nwon bu emu fun [illegible] ki o mu, [illegible] nile Ghana o [illegible], o si ri pe o dun, o tun [illegible] die si, ko ba oju je [illegible] re.

Ọgbẹni Gaitskell dahun pe, emu na jọ omi inu agbon, o si dun lenu gegebi omi inu agbon, o ma dara o.

# Igi Lehin Ogba Egbe Olope



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Adisa Williams ti o jẹ ọkan pataki ninu awọn opomulero fun ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) Ọmọ Eko ni Ọgbẹni yi iṣe ṣugbọn ilu Ibadan lo fi ṣe ibugbe nisisiyi.

## NWON FẸ KỌ ILEWE GIGA SILU KANO.

KANO. Alhaji Ahmadu Dantata ti o je ọmọ ologbe Alasan Dantata lo da imoran wipe, ki gbogbo awon ara ilu Kano da owo jọ bi iwon egba a medogbon poun lati fi ko ile eko giga nigboro ilu Kano.

Alhaji Sir Ahmadu Bello, Oloye Sardauna Sokoto' da irinwo poun ninu owo ile eko giga na. Alhaji Sir Muhamadu Sanusi, Ọba igboro ilu Kano da ọgọrun poun. Ọgbeni A. J. Karoni da irinwo poun.

Gbogbo awon enia nwonyi lo da Ọgọrọrun poun Alhaji Isa Kaita, Alhaji Mustafa Monguno, Alhaji Shehu Ahmadu, Madawakin Kano.

Alhaji Muhamadu Sanni, Seriki Shanu, Kano, da adọta poun. Akojo gbogbo owo ti nwon ri gba le ni ẹgbẹjọ poun lẹsekese. Eyi wu wa o..

## ỌLABISI NILẸ AMẸRIKA

U.S.A. Agbọ irohin wipe Ọlabisi Ajala ti o je ọmọ bibi inu Alhaji Ajala, nigbati o de ilẹ Amẹrika, o kọ iwe kan lati fi fun Ọgbẹni Christian Herter, ṣugbọn awọn ọlọpa da duro nitoripe Ọgbẹni Herter mbẹ ni igbimọ.

Ṣugbọn bi Ọgbẹni na ti nari igbimọ ojọ na ti o si nfe ma lọ sile, ni Ọlabisi tu puru larin awọn Ọlọpa lati sare lọ mu iwe na fun Heter ṣugbọn awọn ọlọpa yara so mọ ti nwon ko jẹ ki o le lọ.

# Awon Olugbimo Nilu Oyinbo



Ilu mẹrindinlogun ni o fi awọn olugbimọ ranṣẹ silu Oyinbo, olu ilu nla London, lati lọ kọ iṣẹ igbimọ ati eto gẹgẹbi ati nse igbimọ nla ni ipade ẹkọ ori ẹkẹjọ ti nwọn nse nilu Oyinbo.

Ọgbẹni Ernest Davies, ọkan ninu awọn olugbimo ilu Oyinbo lọ wa lowo otun ti o mba awon olugbimo meji ti Nigeria soro, lati owo osi si ọtun ni Ọlọla Abengowe t i ilu Ibo ati Oloye S.J. Mariere J.p. ti ile Ighimo apapose Nigeria ati Ọgheni S. A. Pakeman t i o nwo won.




## ỌLỌPA ILẸ AGANYIN WA MU ENIA NI INIṢA

Ọkunrin kan ara Inisha ti o nṣiṣẹ ajagilegbo-ṭogun, ti ṣowo lọ sile Ghana ri lasiko ti o mbẹ nilẹ Ghana ni nwọn sọ pe, ole ja, ogidinleje owo lo si pora. Lẹhin ti nkan yi ti ṣẹlẹ tan, ni ara Inisha na ba wa silu rẹ nilẹ Nigeria.

Awọn ti ọlọpa ri mu nidi ọrọ yi, gbogbo wọn lo nda orukọ ọkunrin ara Inisha yi, nigbati nwọn ndaruko rẹ pupọju ni adajọ ba ṣe iwe ipa wipe ki nwọn lọ mu ara Inisha na wa.

Ọga olori ọlọpa inu pelu awọn enia diẹ, nwọn si lọ gba aṣẹ lọdọ adajọ kotu nilu Ibadan. Adajọ na ni Ọgbẹni M. O. Oyemade lo fi aṣẹ si iwe na.

Nigbati awọn ọlọpa de ile ọkunrin na ni Inisha, lẹhin ti nwọn mu tan nwọn bẹrẹ si tu ile rẹ, nwọn ri apoti Onirin meji, awọn ri moto ayọkẹlẹ kan ati ọpọlọpọ moto ak'ẹru. Nilẹ Ghana ni nwon yio ti ṣe ẹjọ na.

## AYINIKE ATI AYINPADA

(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

**nwon kede ọjọ ijakadi. Ologbo ati Ajapa ko tete de si agbo. Ekute ile ati Okete bẹrẹ ija. Ajapa ti de si ẹhin agbo. Nigbati Okete da Ekute ni Ajapa yan kọngbon kongbon bo si arin agbo, o si darin bayi t e :**

*Gır-r-r-gbo* gidigbo, heya,
Orin :- Bo ba gan mi leṣẹ ọtun
A yi lulẹ bi obọ, Haira
E mi ko je fi oloyọ da fila
Haira.

Ki o to kọrin na delẹ, Ọbọ ti fo sita, o si darin pe
Ọbọ takiti nporo niṣo,
Poro yeye, poro yẹyẹ.

Ni nwọn ba wọya ija piti,piti, piti, Ọbọ gbe Ajapa lati la molẹ Ajapa dahun pe Ayinike bẹni nkan na gbe ọbọ roke rodo o si la molẹ ori ni ọba mu wa sile lati ọjọ na wa ni orun ọbo ti waki molẹ.

(Koiti pari)

## ORISI ỌKỌ OFURUFU MIRAN DE!

Ni ojo 18th oṣu May 1959 ni aramoda oriṣi oko ofurufu kan wa bẹ ilu Eko wo. Ọko ofurufu na, iru rẹ fere je eyiti o mu Ọba obinrin wa sile yi ni odun 1956

Eleyini je alawo dudu o si da bi labalaba, bi o ba ko idi si enia, didun rẹ yio dabi eyiti ara nsan tabi ti ojo nkun.

Sugbon a gbo wipe oko ofurufu titun yi je eyiti o mu Omoba Duke wa si ibi ere Durbar ni Kaduna, eleyi je alarrwo sugbon bakanna lo ri pelu eyin o mu oba obinrin wa o si dabi labalaba, o si je alawo funfun

Oruko ti a gbo pe nwon npe oko ofurufu na ni (Vampires of the R.A.F.).

## IGBIMO AMOFIN BE GHANA WO

Irohin ta si wa leti wipe awon igbimo Amofin nile Nigeria ti o nro biegbe Amofin ile yi yio ti s e n i ilosiwraju, ngbero lati se abẹwo ofin ile Ghana ki nwon si fi we ara w o n w o, bi o ba si tun di inu osu July ti o mbo yi nwon o tun lo be ilu Gesi wo nipa ofin lati fi we arawon wo.

# Awon Olotu Ijoba Ile Nigeria



Nigbati awon Hausa pari ere Durbar tan lojo Saturday ni *Ogbeni Sir Alan Lennox-Boyd* pe apejo awon Olotu ijoba ile Nigeria papo sinu agbala igbadun kan nilu Kaduna.

Die ninu awon enia ti a nwo ninu aworan yi lo peju pese sibi ipade na. Bere lati owo otun Dr Nnamidi Azikiwe. Premier, agbegbe Ila-orun, Sir Ahmadu Bello, Sardauna ile Sokoto, Alhadji Abu Bakare Tafawa, Balewa, Oloye Awolowo, Premier, agbegbe Iwo-orun ati Sir Alan Lennox-Boyd, Sekiteri Ilu Oyinbo.

## Ohun Iyanu Ko Ntan Laiye

Irohin de si owo wa lati ilu Amerika wipe, okan ninu awon ojogbon ile aiye se awari ogbon kan tobe ti o se ero kan ti a le pe ni Aje. (Opeon.)

Oruko ti nwon npe ero aje na ni Opeon. Bi oro kan ba ru enia loju tabi bi awon enia meji ba mba ara won jiyan lori ohun kan. Tabi ewe, bi a ba fe mo olododo larin awon enia meji ti o mba ara won se gbolohun aso, tabi bi ohun kan ba sonu ti a ko mo eni ti o gbe nkan na, ohun ti won o se niyi:-

Enikini yio rojo enu re sinu ero (Aje) yi, bi o ba pari re tan eni keji yio ro tire jade sinu ero na pelu.

Bi nwon ba pari re tan, nwon o yi ero na (wind) nwon o wa joko ti lati gbo esi. Lehin ti ero na ba ronu titi yio wa bere si fohun. Oro ti o ba si so, ododo ni. A gbo wipe awon Olopa ni yio ma lo ero Aje na, ise pupo ni ero na nse, eyi ti a so yi je isebere ninu ise re.


## Kere o !

Ati ni orisirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos



## E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE

LOSOSE, O KUN FUN IROHIN ALADUN



# NIGERIAN TOBACCO COY LTD.

**(INCORPORATED IN NIGERIA).**

Awon Oyinbo Onisowo ewe taba (Nigeria Tobacco Coy Ltd nfe awon ti o ti mo ise Fitter ti nwon si ti yege ninu idanwo re ti ipo re je ekini tabi ekeji ati awon ti o mo ise nipa ero moto ki nwon kowe fun ise ninu ile ise ero won.

Awon ti a ba gba sibi ise yi yio wa fun yiye ise won wo fun odun kan, bi o ba si yege nipa mimo ise na, ao gbe si ipo ifi okanbale (Permanent).

Owo ti nwon o ma gba, ati aye ise won yio joju.

Idanwo won yio gba ojo meji, awon ti a ba si yan yio ri iwe wa gba.

Awon ti o ba ni imo to ni ki o kowe fun aye na ki nwon si so iye ojo ori won, lakaye won, ni ibiti nwon ti nse iseri pelu iye owo ti nwon ngba losu lowolowo ki nwon fi ranse si :-

PERSONNEL OFFICER,
**NIGERIAN TOBACCO COY LTD,**
**P. O. BOX 6, IBADAN**

Gbogbo awon iwe ni ao yewo ni asiri, enikeni ti o ba si kowe ki o ko asiri sara re bayi "Confidential". Fitters T.T. 1 tabi 11, Tabi Moto Mechanic T.T. 1, tabi 11.

Enikeni ko gbodo fi ojulowo iwe eri ti o gba nibi ise ranse ayafi eda re gan-an. Enikeni ti a ko ba pe ti o ba wa, a ko ni da lohun, a ko si ni ba enikeni soro nipa ise yi lori ero isoro (Telephone)

# Adamodi Oba Farakorin

IBADAN - Ọkunrin Agbalagba kan ti o gbe ẹjọ rẹ wa siwaju adajọ Kotu giga nilu Ibadan fun arotunro nipa wipe idajọ ti Kotu kekere ko tẹ on lọrun lori ẹsun pe ọkunrin na nṣe bi ọba kakiri ilu ni Ile-Ifẹ, ti adajọ pe ni olori kunkun enia, alaigbọran ati enia lasan ni adajọ ju si ẹwọn oṣu mẹfa fun ṣiṣe afarawe ọba.

Adajọ kotu giga mu ti ẹwọn kuro, ṣugbọn oni ki o towo bọwe fun ọdun meji lori ọdunrun pọun ẹlu onigbọwọ meji fun aradojọ pọun ẹnikọkan wipe on yio so agbejẹ-mọdi fun ọdun meji. Bibẹko, ki ọdaran na lo ṣe ẹwon re.

# Ayinike Ati Ayinipada

(Apa IV)

(Lati Qwọ Ẹṣo)

Olegbo gba iyi lọjọ ti o da gbogbo awọn ẹranko gbogbo awọn ọmọ ẹranko gbe kọrun dele, lati ọjọ na wa ni nwọn ti npe Ologbo ni Musi eyi ti awọn ẹlomiran sọ di M u s u nisisiyi.

Nigbati o di owurọ ọjọ kan ni Ajapa mu iṣu meje o di o diru lọ sile Ologbo o ki i ku arọ tan, lo ba sọ ẹru kalẹ, o dọbalẹ o kii o ni ẹ jọwọ, ọdọ nyin ni mo wa, iru egbogi ti ẹ fi nda wọn ninu ijakadi yẹn ni mo fẹ ki o ṣe fun mi; nitori rẹ ni mo ṣe mu iṣu yi wa fun nyin.

Ologbo dahun pe ha a a! ẹnyin ọmọ araiye, ẹ ẹ ko ṣe finu han, ẹniti o ba finu rẹ han ẹ ẹnyin na ni yio pada ṣe oluwarẹ ni jamba. Tabi o ko gbọ bi nwọn ti nkọrin wipe:

"Enia ko ṣe finu han, bo ba lọgbọn fisi kun ara rẹ, gbogbo enia lo di eke, aiye di aiye agunla".

Ologbo taku pe on ko ni fi idi ayinike han Ajapa. Ajapa mbẹbẹ, o nralẹ anu rẹ si ṣe Ologbo depo ti o fi ayinike han Ajapa.

Ajapa fi onde Ayinike sidi o bẹrẹ si yan kakiri. Bi o ba de ibikan ti awon omo ẹranko po a ma pe won lati waja a si ma da won. Irohin ti wa kan wipe Ajapa yio ṣe nkan ninu ijakadi ti o mbo yi.

(Wo yoku loju ewe kẹrin)

# Afese Kan Pa Meje

Gbogbo enia lo ti mọ wipe, nigbati ọdun Keresimesi ba nsun mọ etile, akoko na ni iṣẹ ma npa awon aranṣọ laiya, ti ọwo won si ma udi, Ọkunrin kan ti o je aranṣo ti o si jẹ ẹlẹrẹgbẹ enia ti o si le dapara wa nigbakan, ti iṣe po fun bayi ni asiko ti odun Keresimasi mbo. Latigba ti o ti de ibi iṣẹ, ko ri aye jẹun lati owuro bi ki o ṣa pari awon aṣo na lokan rẹ.

Nigbati o to bi iwon agogo mokanla lo gbo ti obinrin kan npolowo bota, nigbati aranṣo na gbo o ranti pe on koiti jẹun lati owuro o pe e o ra bota, o ra bnrẹdi, lo lo ba jẹun, o yo ṣugbon ko ranti fi nkan de bota ti o ku o nowo gan iṣẹ rẹ o si mba iṣẹ lo.

Awon eṣinṣin si ṣurubo bota na. Ri aranṣo na ti gbe ori soke lo ri awon eṣinṣin ti o ṣurubo bota na mole, o wipe ha! bota mi o si mu irepe aṣo kan o fi ju awon eṣinṣin na o si pa meje ninu won.

O ya lẹnu wipe on pa meje lẹkan ṣoṣo. Inu rẹ dun o si fun ara rẹ ni suna bayi wipe, "Emi afẹse kan pa meje" o wipe bi enia ko tile se iṣẹ aranṣo na, eyiyi na to mi gbe kiri, o si bẹrẹ si pokiki ara rẹ kiri pe on afẹse kan pa meje O ko orukọ yi si ara Beliti. o si fi gba inu.

Nigbogbo akoko yi iṣe ni okiki re nkan jakẹ jado ni gbogbo awọn ilu bi o ba nkoja lo, apegba ni gbogbo enia yio ma pe e, on na yio si ma dahun pe ẹ gbere o, aiye ayẹ nyin o. Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ lọsẹ ti o mbo, eo gbo gegebi o tise lo ba awon omiran ja.

(Koiti Pari)

# Omo Egbe N.P.C Gbe Egbe Afenifere Lese.

"Bi o pe, bi o ya, otito ni yio leke", eyi ni ohun na ti mo fi dupe lọwọ Ọlọla Mallam Abu Bakar Kuguma, okan ninu awon Olugbimo Ijoba apapoṣe nigbati o mba awon alatilehin ẹgbe won (N.P.C) soro nilu Sudawa ni agbegbe Kano lọse to koja.

O kesi awon obinrin ile Ariwa wipe ki nwon mu ẹkọ ni pataki julo nitoripe nwon ni iṣẹ pataki lati se ninu ise iselu ati alafia ilu. Irufe gbolohun bayi ti enikeni kole ni ireti pe yio jade lenu omo ẹgbẹ N.P.C. ni ọpọlọpọ ọdun si.

A ni lati se iranti wipe gbolohun yi papo pelu oro ti ẹgbẹ Afenifere (Action Group) tẹnumo ninu igbimo apero eto iselu ti a lo se nilu Oyinbo gbehin yi, wipe, ki a mase di awon obinrin lowo lati dibo gẹgẹbi o ti jẹ ẹtọ iṣẹ won ti nwon ni lati ṣe ninu iṣe iṣelu ati ilosiwaju ilẹ Nigeria.

O han gedegbe nisisiyi fun enikẹni lati mọ wipe ẹgbẹ N.P.C. mọ ohun ti o tọ ṣugbon nwon ko jẹ ṣe ni, nitoripe awon ko fẹ ki awon Talakawas, (iyen ni awon enia ilu ti ki iṣe iran Ọba) jẹ ninu anfani ijọba ilaju ti asiko yi.

Nisisiyi ti Mallam Abu Bakar Kuguma ti la ala tabi o ri ni ojuiran wipe awon obinrin Oke-Ọya ni lati se iṣẹ won ninu iṣelu ti ilẹ Nigeria wa titun yi, mo ni ireti wipe awon aṣiwaju ẹgbẹ N. P.C. yio pa ero won da nisisiyi fun ilọsiwaju ilẹ Oke-Ọya.

"Nisisiyi, mo fi eyi kesi awon Talakawas, gbogbo awon enia ti o mbẹ nilẹ Oke-Ọya wipe ki nwon mọ ọrẹ won yato si ọta won. Nitorina ki nwon kọ ẹgbẹ N.P.C. patapata, ki nwon si fi ara mo ẹgbẹ Afenifere. (Action Group) ki nwon dibo fun u gidigidi.

B. A. CAREW
16 : 5 : 59


# L. E. D. B.

# Free Hold Houses On Show AT Suru-Lere

## 18th MAY - 30th MAY, 1959.

COME AND INSPECT.

Houses open for inspection daily at Akerele Road and Ogunlana Drive, Itire Road Estate, off Itire Road, Suru-Lere,

Free Bus Service to the Estate and Return from Bread fruit Street (L.E.D.B. Information Office) at 4.15 p.m. on Wednesdays and Saturdays 20th, 23rd, 27th and 30th inst. respectively, also on Monday 18th inst.

J. W. HENDERSON.
Chief Executive Officer.

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFE" LAGOS

P. O Box 467 Phone 23310

VOL. XI. NO. 625. SATURDAY MAY 23 - MAY 29...


# Ayeye Ominira Oke-Aya

Nisisiyi ti ariwo awuye-wuye ti ṣiṣe ayẹyẹ ilẹ Oke-Ọya gba aṣẹ is'akoso ijọba ara-ẹni pari yi, yio jẹ didun inu wa ati gbogbo enia ilẹ Nigeria bi awọn aṣiwaju wa, paapa awọn akonijẹ wa bi Ọlọla Sir Ahmadu Bello, ti iṣe Olotu ijọba Ariwa, Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe, Olotu ijọba Ila-Orun ati Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Olotu ijọba Iwo-Orun ba le fiyedenu ki nwọn tẹle ọrọ ti a gbọ wipe Akọwe agba nilu Oyinbo, Ọgbẹni Lennox-Boyd sọ wipe ibo ti ao di ti o mbọ yi yio lọ tara pẹlu irọrun laiko ni s' iwa rudurudu, iwa jagbajagba, iwa ki ijọba kan ma jẹki awọn ijọba Alatako tabi ẹlomiran ṣe ikede lati ṣe alaye fun awọn ti yio dibo yan enia ti yio mu opo ijọba dani.

Nitori eyi, a fi wosika wa yi kesi Ọlọla Sir Ahmadu Bello ki o ba wa ṣe ikilọ fun awọn ẹnia rẹ, ani awọn ọmọ ẹgbẹ N.P.C. ki o ma ṣe si idikowọ mọ fun awọn ẹgbẹ miran nilẹ Oke Ọya ki gbogbo wa le jijọ k'ọmọjubọ lọjọ idibo gbogbo-gbo ti o mbọ yi.

## Ayinike Ati Ayinipada

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Oṣupa koiti lẹ, ti ọkiki fi nkan kakiri ilu wipe uṣe ni o nda wọn kakiri. Awọn miran sọ wipe ẹgandi lo fi nda wọn, omiran sọ pe, rara ẹfasẹ ni, bẹni awọn miran sọ pe ẹpa-iṣana lo fi nda wọn, omiran si wipe agbeledi ni.

Ni gbogbo bi Ologbo ti ngburo Ajapa inu rẹ ndun pe egbogi ti on ṣe fun jẹbẹ laifa ọrọ gun Oṣupa lẹ,

(Wo yoku loju ewe karun)


OMỌRẸLA

is the ever-ready way to get rapid relief from Cough, Cold, Fever and all Children ailments.

This is a well tried remedy

A Chemist Product

Commercial Medicine STORES

LAGOS & IBADAN.




## Azikiwe Si Ibuso Moto Nilu Aba



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Dokita Azikiwe, nigbati o de silu Aba lati si ibuso Moto ti a fi oke kan Poun ko si ilu Aba. Irohin ti a gbo fihan wipe sisi ibuso Moto na ladun o si l'arinrin. Diẹ ninu awon to wa nibẹ ni Margaret Ekpo' E. Onuigbo, ati A. N. Onyiuke.


LAGOS RACE CLUB

JUNE MEETING

Saturday 30th May, 6th, 13th, 20th And 27th June, 1959.

Racing starts at 2.45 p.m. each day of the meeting.

DECLARATION

To be made at the Secretary's Office between the hours of 5 p.m. AND 6 p.m. each day preceding the day of the meeting.

ADMISSION: FIVE SHILLINGS PER DAY INCLUDING ENTERTAINMENT TAX.

CHILDREN

No children under the age of 14 years will be permitted ot enter the members enclosure.

# LAGOS RACE CLUB

## JUNE MEETING 1959

## Saturdays 30th May, 6th, 13th, 20th And 27th June, 1959.

### FIRST DAY

| | FIRST DAY | START |
|---|---|---|
| RACE NO 1 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO 4 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | THE QUEEN'S OWN NIGERIA REGIMENTAL STAKES Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |

### SECOND DAY

| | SECOND DAY | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45p.m. |
| RACE NO. 2 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | THE SIR ADEYEMO ALAKIJA MEMORIAL PRIZE Six Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |

### THIRD DAY

| | THIRD DAY | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE NO. 3 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4- 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO 6 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO 7 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 45 p.m. |
| RACE No 8 | THE NIGERIA DERBY Twelve Furlongs | 6. 15 p.m. |

### FOURTH DAY

| | FOURTH DAY | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m |
| RACE No. 3 | Six Furlong Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m |
| RACE NO. 7 | POLO SCURRY | 5.45 p.m. |
| RACE NO 8 | THE CORONATION PRIZE Ten Furlongs Top Division | 6.15 p.m. |

### FIFTH DAY

| | FIFTH DAY | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE NO. 2 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3.30 p.m. |
| RACE NO. 3 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4.00 p.m. |
| RACE NO ▾ | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4.30 p.m. |
| RACE NO 5 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 5.00 p.m. |
| RACE NO. 6 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 5.30 p.m. |
| RACE NO 7 | Five Furlongs Handicap Top Division | 6.00 p.m |


## AMODU JOYE BALOGUN AGO-ODO

ABEOKUTA. Ogbeni Amodu eniti o ti je okan ninu awon Juri ti kotu Ake, Grade "A" Court, ni ijoba ibile Egba ro, ti nwon si fi je oye Balogun fun fun gbogbo awon ara Odo ati ara Oke-Ona nigboro Abeokuta.

Lasiko ti nwon njawe oye le lori, ese gbogbo awon ijoye ilu awon igbimo ilu, awon Kiriyo ati Imale lo peju sibi ariya ifini joye na, awon ara ati ebi gbogbo lo gbaruku ti i lehin.

Konigbagbe ni iṣele ojo ifini joye yi je fun Balogun titun yi nitoripe larin meji ibiti gbogbo enia mba yo ti oye re ni awon ara, ebi, ibatan, se esin kan ni oso repete, ti nwon si fa wa fi ta Balogun ti tun na lore.

Nigbati nwon fe fi esin na ta lore, olori awon ebi so pe, "Nitori imo re ti o ni ati oye ori re, ati ife ti o ni si gbogbo wa lo je ki o ga de iru ipo ti o de loni yi. A lero pe iwo ko ni gbagbe iru awon ti o se atilehin fun o titi de ipo ti o wa loni yi. Ki Olorun Oba wa pelu re O gun esin re, gbogbo enia si ho gee wipe "Baba Sali" wa see pe.

## AWON OMO OGUN OLOPA YIO SERE FUN OMOBA

A gbo irohin wipe, bi o ba di ni ojo 28th osu May 1959 ni ojo ti awon olopa omo ogun oju omi da lati se ariya ni gbalasa odan fi ye omoba (Duke of Gloucester) ati iyawo re si Gomina agba ati enia pataki-pataki yio peju-pese sibe nigbati Omoba na ba de si Eko. Nwon a jo, awon a si yan pelu.

Tani yio tete de ibe o ?

# ELETI - OFE D'ARABA

